# Ewì Gẹ́gẹ́ Bí Ètè Ogun Jíjà Láwùjọ

Luqman Abísọ́lá Kíaríbẹ̀ẹ́
Ẹka-Ẹ̀kọ́ Ìmọ̀ Ẹ̀dá-Èdè Àti Èdè Adúláwọ̀
Yunifásitì Ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun, Nàìjíríà.
luqman.abisola@gmail.com tàbí luqman.abisola@yahoo.com

## Àṣamọ̀

Oríṣìíríṣìí ète ni àwọn jagunjagun máa ń ṣàmúlò láyé àtijọ́ láti fi ṣẹ́gun ọ̀tá. Díẹ̀ lára àwọn ète wọ̀nyí ni ìdẹ́rùbani, olè jíjà, agbára oògùn àti bíba irè oko àwọn ọ̀tá wọn jẹ́. Àwọn iṣẹ́ ìwádìí ti wáyé lóríṣìíríṣìí lórí ogun jíjà láwùjọ Yorùbá ṣùgbọ́n kò sí iṣẹ́ ìwádìí kan gbòógì tó ṣe àgbéyẹ̀wò ewì gẹ́gẹ́ bí ète ogun jíjà ní pàtó, ní kíkún. Lọ́nà àti dí àlàfo yìí, iṣẹ́ ìwádìí yìí fi ojú ìmọ̀-ìtàn-mọ́-lítíréṣọ̀ ṣe àtẹ̀gùn láti ṣe àgbéyẹ̀wò ewì gẹ́gẹ́ bí ète ìjagun ní àwùjọ Yorùbá. A mọ̀-ọ́nmọ̀ ṣàṣàyàn àwọn ogun tí ó ti wáyé nínú ìtàn láwùjọ Yorùbá nínú èyí tí wọ́n ti ṣàmúlò ewì láti ṣẹ́gun ni. A fi ọ̀rọ̀ wá àwọn àgbà àti àwọn tó nímọ̀ nípa ogun lẹ́nu wò. Bákan náà ni a ṣe ìtúpalẹ̀ àwọn ewì tí wọ́n lò, lọ́nà àti mọ ìdí tí ète náà fi mú ọ̀tá tí wọ́n dẹ ẹ́ fún. Orin lóríṣìíríṣìí àti oríkì ni iṣẹ́ ìwádìí ṣe àfihàn pé wọ́n lò gẹ́gẹ́ bí ète láti mú ọ̀tá nínú ogun tí a yẹ̀wò. Bákan náà ni ó hàn gbangba nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí pé ewì gẹ́gẹ́ bí ète mú àwọn ọ̀tá nítorí ọ̀nà tí wọ́n gbà lò ó fún ìdẹ́rùbani, ìdájàsílẹ̀, ìtannijẹ, ìránnilétí, ẹ̀bẹ̀ àti àyẹ́sí. Ìgúnlẹ̀ iṣẹ́ ìwádìí ni pé idà olójú méjì ni ewì jẹ́. Bí a ṣe le lò ó gẹ́gẹ́ bí ète ìdógunsílẹ̀ náà ni a lè lò ó láti pẹ̀rọ̀ ogun. Nítorí náà, ewì tí í ṣe ogún ìbí Yorùbá ni a le ṣàmúlò láti dènà tàbí pẹ̀tù sí aáwọ̀ kí ó tó di ogun lọ́nà àti mú àlàáfíà àti ìdàgbàsókè bá àwùjọ.

### 1.0 Ogun Àti Ète Ogun Jíjà Láwùjọ Yorùbá

Kò sẹ́ni tó le sọ pàtó ìgbà tí ogun jíjà bẹ̀rẹ̀ ní àwùjọ ènìyàn. Àṣà kan tó kárí gbogbo àwùjọ àgbáyé ni. Nígbà tí èrò ọ̀wọ́ ènìyàn méjì kò bá dọ́gba, tí ọ̀kan kò gbà fún èkèji, tí wọn kò sì ṣetán láti yanjú ẹ̀ ní ìtùbí-ìnùbí, dandan ni kí ohun náà di ìjà, èyí tí ó sì le yọrí sí lílé ẹ̀mí ara ẹni kiri. Bí èyí bá ti ṣẹlẹ̀, ọ̀rọ̀ ti já sí ogun nìyìí. Bí a bá wò ó láti inú ìtán ọjọ́un ilẹ̀ Gíríìkì, oríṣìíríṣìí ni àwọn ogun tó gbajúmọ̀ tí àwọn ènìyàn àwùjọ náà bá àwọn ìran mìíràn àti àwọn ara wọn jà. Lára àwọn ogun tó gbajúgbajà tí wọ́n jà ni Ogun *Troy*, Ogun *Corinthian* láàrin 395 BC sí 387, Ogun *Persia* 499 BC sí 488 BC, Ogun

*Peplonnesia* 431 BC sí 404 BC (Fitzgerald, 2017), Ogun ilẹ̀ *Asia*, bẹ̀rẹ̀ lọ́dún 334 BC àti wíwọ ilẹ̀ *Egypt* láàrin 332 BC sí 331 BC (Pomeroy, 2004) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bákan náà nínú Bíbélì, oríṣìíríṣìí ogun ni ó wáyé láàrin àwọn ọmọ Ísráẹ́lì àti àwọn ọ̀tá wọn gbogbo. Lára àwọn ogun mánigbàgbé inú Bíbélì ni ogun Ábrámù àti àwọn ará Sínáì (Bábílónì) (Jẹ́nẹ́sísí 14), Ọba Fáráò àti àwọn Ísráẹ́lì (Ẹ́kísódù 14), Ísráẹ́lì àti àwọn Ámálékì (Ẹ́kísódù 17; 8-16), Ìtakora àwọn ọmọ Ísráẹ́lì pẹ̀lú ara Mídíánì àti Móábù (Númérì 31:11-11), Ísráẹ́lì àti ara Jẹ́ríkò (Jọ́ṣúà 6), bí àwọn ará Fílístínì ṣe gba Àpótí-Ẹ̀rí (1 Sámúẹ́lì 4:1-11), (Shiffered 2015) àti (Cleretian Publication 2003). Bákan náà ni ọ̀rọ̀ ṣe rí nínú *Quran*. Lára àwọn ogun tí a rí kà nínú *Quran* ni (Ogun *Badr*; *Quran* 8:5-8), Ogun *Uhud* (Quran 3:169), Ogun *Khandaq* (*Moat*) tabí *Ahzab* (*Quran* 33:10-11), Ogun *Khaibar* (*Quran* 48:18) àti Ìborí *Makkah* (*Quran* 17:81). Èyí fi hàn pé láti ìgbà ìwáṣẹ̀ ni ọmọ ènìyàn tí ń bára wọn ja ogun, kò sí ibi tí a kì í tí kó adìyẹ àlẹ́ sì ni ọ̀rọ̀ ogun jẹ́.

Bí àwọn wọ̀nyí tilẹ̀ jẹ́ ogun ọlọ́jọ́ pípẹ́, àwọn ogun kan wà tí ọjọ́ wọn sún mọ́, bákan náà ni àwọn kan ń lọ lọ́wọ́. Lára àwọn ogun tí ọjọ́ wọn kò jìnnà tó àwọn tí a tọ́ka rẹ̀ lókè ni Ogun Abẹ́lé Ilẹ̀ Amẹ́ríkà (1861-1865), Ogun *Franco-prussian* (1870-1871), Ogun Àgbáyé I àti II (1914-1918 àti 1939-1945) àti Ogun Abẹ́lé Ilẹ̀ Nàìjíríà (1967-1970), wo Gate (2001) àti Townshend (2000) fún àpẹẹrẹ síwájú sí i. Lára àwọn ogun tó ń lọ lọ́wọ́ lágbàáyé ni Ogun Abẹ́lé orílẹ̀-èdè Sòmálíà (1991 di àsìkò yìí) àti Ogun Abẹ́lé Orílẹ̀-èdè Ààrin Gbùngbùn Ilẹ̀ Adúláwọ̀ (2012 di àsìkò yìí). Kí ilẹ̀ Yorùbá tó dara pọ̀ mọ́ àwọn ẹ̀yà mìíràn láti di orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ni ogun ọlọ́kan-ò-jọ̀kan ti máa ń wàyé láàrin wọn. Lára àwọn gbajúgbajà ogun tó wáyé ní ilẹ̀ Yorùbá ní Sẹ́ńtíúrì Kọkàndínlógún ni Ogun Òwu (1813-1814 àti 1821-1826), Ogun Èkìtì Parapọ̀ (Ogun Kírìjí), Ogun *Dahomey* (1726-1823), Ogun Ìjàyè (1860-1862) àti Ogun Bátẹ̀dó (Arógundádé, 2017).

Ẹ̀wẹ̀, Yorùbá kò fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú ọ̀rọ̀ ogun rárá. Èrò, ìgbàgbọ́, àṣà, ọ̀rọ̀ ẹnu, ẹ̀sìn àti àwọn ọ̀nà ìgbé-ayé wọn gbogbo fi èyí hàn. Yorùba bọ̀ wọ́n ni; “Ogún níí ṣini mú, èpè kì í ṣini jà”. Ohun tí èyí fi hàn ni pé ogun kò mọ ojú ẹnikan bóyá ènìyàn lọ́wọ́ nínú rẹ̀ tàbí kò lọ́wọ́ nínú rẹ̀. Èyí tún fi ìjànbá tí ogun ń ṣe hàn. Yorùbá a tún máa sọ pé, “Ẹni tí kò mogun níí sọ pe kí ogun ó dé, ogun kò rí bí ìyan bẹ́ẹ̀ ni kò rí bí ẹ̀kọ”. Èyí tọ́ka sí pé ọ̀rọ̀ ogun kì í ṣàwàdà, ọ̀rọ̀ ìparun ìran, ẹ̀yà àti àwùjọ ni. Bí ọ̀rọ̀ ogun ṣe lágbára tó Ifá kò fi ojú kékere wo ìjàǹbá, ìparun àti ìṣòfò ẹ̀mí tí ó máa ń mú dání. Ẹsẹ ifá kan sọ̀rọ̀ nípa ogun nínú Yémitàn àti Ogundélé (1970):

Apá ẹran ń bẹ lọ́wọ́ Lánlọṣe,
Agọ̀ màrìwò ń bẹ lọ́wọ́ Làrùba.
Mo f’ògo,
Mo r’ógo,

Mo wò'gbẹ̀hìn ọ̀ràn bí yíò ti sunà, sùnà sí.
Èmi wò gbẹ̀hìn ọ̀ràn sunà, sùnà sí:
L'ó dífá f'ọ̀ba l'Éwìí Adó.
Ológoṣẹ́, àwo wọn l'Óde Àgéré;
Àrẹ̀rẹ̀kosùn, awo Òkè Ìjerò;
Èbùrẹ́ jẹ̀gìjẹ̀gì, awo ọrùn èbè,
Awo inú poro oko:
Ló dífá f'ọ̀ba l'Áròde Ọ̀yọ́
Ó dìgbà kìíní,
Ọba Ọlọ́yọ̀ọ́ ń gbógun rÒde Èwí:... (*Ojú Ọ̀ṣùpà*: 70-76)

Ninú ẹsẹ Ifá yìí, Ológbòjìgọ̀lọ̀ lawo Èwí Adó, òun náà ló sì bá a sa Ifá tí apá ogun kò fi ká ilú rẹ̀ lásìkò tí Ọlọ́yọ̀ọ́ fẹ́ láti ja ilú rẹ̀ lógun fún ìgbà àkọ́kọ́. Torí pé ìjàǹbá ni ogun jẹ́, Ọlọ́yọ̀ọ́ dẹ tàkúté obìnrin sí baba aláwo yìí, ìyẹn sì fún àwọn ère agbára rẹ̀ ní èèwọ̀ jẹ tí ọwọ́ ọ̀tá fi tẹ Èwí Adó àti àwọn ènìyàn rẹ̀. Ẹsẹ Ifá yìí ń tọ́ka sí i pé òpin ọ̀tá láàrin ọmọ ènìyàn ni ogun jẹ́. Dídẹ obìnrin síni sí jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ète tí àwọn jagunjagun àtijọ́ máa ń ṣàmúlò láti jagunṣẹ́gun. Ó tún fi hàn pé ète ogun jíjà kò pín sí ibikan ṣoṣo. Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ló le gbà yọ.

Oríṣìí ogun méjì ni Adéoyè, (1979:259) tọ́ka sí; ogun àdájà àti ogun àjàkúakátá. Ogun àdájà ni ogun ayé tí ẹnìkọ̀ọ̀kan ń dá jà lábẹ́ aṣọ, tí ó ṣe é ṣe kí ẹnikèjì má gbọ́ si. Àpẹẹrẹ èyí ni ogun ayé, ogun àjẹ́, ogun elénìní àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ogun àjàkúakátá ni ogun ọ̀kọ̀ àti àdá, ogun ọfà àti ìbọn. Èyí kì í ṣe ogun ànìkanjà rárá, àjọọjà ni. Àpẹẹrẹ ogun yìí ni àwọn Ogun Èkìti Parapọ̀, Ogun Ìjàyè, Ogun Òwu, Ogun Kírìjí àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ tí a ti mẹ́nu bà lókè. Adébọ̀wálé, Olúmúyìwá àti Aṣíwájú (2018) àti Fáṣehùn tilẹ̀ tọ́ka rẹ̀ pé oríṣìí ogun kan ni ogun ẹnu náà jẹ́. Àwọn onímà yìí náà gbà pé Oríṣìíríṣìí ni ète tí àwọn jagunjagun ìgbàanì máá ń lò láti já ogun. Lára wọn ni ríró èso igi, wíwọ̀lú lójijì, odi mímọ àti títan ọ̀tá mú. Lára àwọn ohun tí wọ́n fi le tan ọ̀tá mú ni oúnjẹ, dúkìá, obìnrin, èdè àyàn (ohùn ìlù), èéfín àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn ète mìíràn tí Dáramọ́la àti Jẹ́jẹ́ (1975) tọ́ka sí ni kòtò gbígbẹ́ sí ibi tí ọ̀tá kò mọ̀ tẹ́lẹ̀ ti ó ti lè rọ́ lù ú àti ṣíṣáná bọlé ọ̀tá láìròtẹ́lẹ̀. Arógundádé (2017) tilẹ̀ ṣe ọ̀pọ̀ àlàyé lórí pé ète oríṣìíríṣìí ni àwọn ẹ̀yà Yorùbá ṣe àmúlò nínú àwọn ogun tí wọ́n jà ní Sẹ́ńtíúrí Kọkandínlógún. Awẹ́ (1975) tún ṣàlàyé síwájú sí i pé oríkì àwọn jágunjagun tí a sọ di ohun ìdánimọ̀ wọn, tí àwọn onílù ogun wọn fi máa ń kì wọ́n lójú ogun jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú ète tí àwọn jagunjagun fi máa ń dọdẹ ara wọn. Àpẹẹrẹ pàtàkì kan tí Awẹ́ (1975) tọ́ka sí ni Ogun Jálumi (1878) níbi tí Fábùnmi àti àwọn ọmọ ogun Èkìtì ti fi ohùn ìlù oríkì ọmọ Balógun Ìbíkúnlé, Akíntọ́lá "Kìnìún Oníbùdó" (269-270) tan Òsì Balógun Ìbàdàn, Ìlọ̀rí àti àwọn ọmọ ẹ̀yìn rẹ̀ mú. Bí a bá le fi oríkì tí a fi èdè àyàn gbé kalẹ̀ tan jagunjagun kan mú gẹ́gẹ́ bí ó ṣe ṣelẹ̀ nínú àlàyé tí Awẹ́ ṣe yìí, a jẹ́ pé ète ogun

kan gbòógì ni ewì jẹ́. Finnegan (2012) náà kò ṣàì tọ́ka sí i pé àwọn ènìyàn ilẹ̀ Adúláwọ̀ máa ń lo èwì láti fi ṣe kóríyá fún àwọn jagunjagun lójú ogun.

Yàtọ̀ sí pé a fi ewì tan jagunjagun mú bí Awẹ́ (1975) ṣe tọ́ka sí i yìí àti pé a le fi ṣe kóríyá gẹ́gẹ́ bí Finnegan (2012) ṣe sọ, àwọn ìtàn ogun mìíràn níbi tí a ti ṣe àmúlò ewì gẹ́gẹ́ bí ète ogun tún fi hàn pé a le fi ewì dẹ́rù bá ọ̀tá, a le fi tani jí, a le fi da nǹkan rú mọ́ ọ̀tá lójú, a le fi ránni léti ète tí a ti pa kalẹ̀ de ọ̀tá, a sì le fi dẹ́rọ̀ ìjà. Ọ̀wọ́adé (2018) ṣe àlàyé pé a máa ń fi orin ṣe ìpè, kéde ogun, ṣáátá ọ̀tá, fi ẹ̀hónú hàn àti ṣe ìkìlọ̀ lójú ogun. Ohun kan tí ó tún ṣe kókó láti kíyè sí nípa àlàyé Awẹ́ yìí ni pé ewì lágbára torí pé ọ̀rọ̀ ni a fi gbé e kalẹ̀. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, “Ọjọ́ tí ogun yóò tú Ìkìrun, ọ̀rọ̀ ló tẹ́lẹ̀ rẹ̀”. Bí èyí bá rí bẹ́ẹ̀, a jẹ́ pé ìrúfẹ́ ọ̀rọ̀ tí ó lágbára láti tú odidi ìlú kì í ṣe ọ̀rọ̀ ṣákála kan lásán, ọ̀rọ̀ tó nípa lára olùgbọ́ rẹ̀ ni. Gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹ́ pé èdè tó nípa lára olùgbọ́ ni Fábùnmi àti àwọn ọmọ ogun Èkìtì fi tan odìdi Òsì Balógun Ìbàdán àti àwọn ọmọ ogun rẹ̀ mú. Kí ọ̀rọ̀ tó le nípa lára ju ọ̀rọ̀ lásán lọ, a jẹ́ pé èdè afìmọ̀sílárahan tíí ṣe èdè-ọnà ni a fi gbé irú ọ̀rọ̀ náà kalẹ̀. Bí a bá sọ̀rọ̀ nípa èdè iṣẹ́ ọnà, èdè ewì náà ni à ń tọ́ka sí torí pé èdè ewì yàtọ̀ sí èdè ojoojúmọ́, inú rẹ̀ sì ni fífi èdè pàrokò wọ́pọ̀ sí jùlọ (Riffaterre, 1978). Fún ìdì èyí ó yẹ kí á le sọ̀rọ̀ nípa ewì àti bí ó ṣe máa ń mú àwọn olùgbọ́ lọ́kàn.

## 2.0 Ewì àti Èdè Ewì

Orúkọ mìíràn fún ewì ni àròfọ̀. Ọ̀kan lára àwọn ẹ̀yà tí lítíréṣọ̀ pín sí káríayé ni ewì jẹ́. Ọ̀nà láti fi èrò inú ẹni hàn ní ìlànà onílàjilà níí ṣe pẹ̀lú. Èdè inú ewì a máa ki, kì í gùn jù, kò sí àyè fún ìfọ̀rọ̀ṣòfò nínú rẹ̀, aboyún ọ̀rọ̀ ni ewì máá ń jẹ́. Kí àṣà mọ̀-ọ́nkọ-mọ̀-ọ́nkà tó dé ni ẹ̀yá Yorùbá ti ń ké ewì, irúfẹ́ ewì yìí ni a mọ̀ sí ewì alohùn. Àwọn ọ̀nà mẹ́ta pàtàkí tí Ogúndèjí (1991) tọ́ka sí pé a le pín ewì alohùn Yorùbá sí nígbà tí a bá lo ìwéhùn àti ọ̀fun ṣíṣe gẹ́gẹ́ bí òṣùwọ̀n ni àrángbọ́, ìṣàré àti orin. Àrángbọ́ ni ewì tí a gbé jáde nígbà tí ìlànà àgbéjáde rẹ̀ kò bá yàtọ̀ sí ìgbà tí à ń sọ̀rọ̀ ojoojúmọ́. Àpẹẹrẹ irúfẹ́ èwì bẹ́ẹ̀ ni oríkì, ọfọ̀, àlọ́ àpamọ̀, àrọ̀, ẹsẹ Ifá àti òwe. Ìṣàré ni ewì tí a gbé jáde nígbà tí à ń ṣe ọ̀fun tàbí rán ọ̀fun kí á tó gbé e jáde. Àpẹẹrẹ èyí ni ẹ̀ṣà egúngún, ẹkún ìyàwó, ìjálá, olele, yùngbà, rárà, ìgbálá àti bẹ́ẹ̀ lọ. Orin ni tìrẹ̀ ni ìlànà rírán tàbí díndín ohun èyí tó gunpá ju àwọn méjì ìṣáájú lọ, èyí ló sì fa kí ó ṣe e gbè, jó, lúlù tàbí ṣápẹ́ sí dáradára. Gẹ́gẹ́ bí èrò Sotunsa (2005), ọ̀kàn pàtàkì tí a kò gbọ̀dọ̀ yọ sílẹ̀ nínú ọ̀nà tí ewì alohùn pín sí ni èdè àyàn jẹ́. Sotunsa (2005) sọ pé bí àrángbọ́, ìṣàré àti orin ṣe dá dúró gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà ewì alòhùn Yorùbá ni ó yẹ kí èdè àyàn náà dá dúró. Èró yìí ló mú wà gbà pé dipò mẹ́ta tí àwọn onímọ̀ lítíréṣọ̀ ìṣáájú pín ewì alohùn Yorùbá sí, mẹ́rin ni ó yẹ kí ó jẹ́.

Èdè ewì tún jẹ́ àrímáleèlọ àwòpadàsẹ́yìn nínú àgbékalẹ̀ èwì Yorùbá. Èdè gan-an ló máa ń ṣọ bí akéwì ṣe dáńgájíá tó. A máá dùn ún gbọ́ létí ju èdè ojoojúmọ̀ lọ. Èyí ló fà á tí àwọn ìpèdè tó wà nínú àkámọ́ wọ̀nyí fi dùn ún gbọ́ létí

ju àwọn tí kò sí nínú àkámọ́ lọ; Àlàkẹ́ **(Alálàkẹ́), Àdùnní (Aládùnní), òjò (eji), ọmọ olòṣì, (olòṣì ọmọ), ilẹ̀ ń ṣú lọ (ọjọ ń rebí tàná/òòrùn ń rebi àtiwọ̀)** àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Gbogbo àwọn ìpèdè tí a fi sínú àkámọ́ wọ̀nyí jẹ́ èdè ewì, torí èyí ni wọ́n fi dùn ún gbọ́ létí ju àwọn tí kò sí nínú àkámọ́ lọ.

Bí a bá wáá wo àwọn aáwọ̀ tó máa ń ṣẹlẹ̀ láwùjọ, kékeré kọ́ ni ipa tí èdè ewì ń kó nínú bíbẹ̀rẹ̀ wọn. Yorùbá bọ̀ wọ́n ní, "Ọwọ́ níí ṣíwájú ijó, orin níí ṣíwájú ọ̀tẹ̀". Bákan náà ló jẹ́ pé ewì a máá kó ipa tó jọjú nínú ète ogun jíjà gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe sọ. Báyìí, a ó gbìyànjú láti wo bí a ṣe lo ewì gẹ́gẹ́ bí ète nínú àwọn àṣàyàn ìtàn ajẹmógun tí a yàn láàyò.

## 3.0 Àgbéyẹ̀wò Ewì Gẹ́gẹ́ bí Ète Ogun Jíjà

Ní báyìí, a máa ṣàgbéyẹ̀wò ewì gẹ́gẹ́ bí ète ogun, irúfẹ́ ewì tí a lò, bí a ṣe lò ó àti ìdí tí ète náà ṣe mú ọ̀tá tí a pa á dè, tí aṣàmúlò ète ewì náà sì ṣe fi bẹ́ẹ̀ ṣẹ̀gun ọ̀tá rẹ̀. Láti inú àwọn ìtàn ogun tí a sọ ni a ti fa àwọn ohun tí a mẹ́nu bà wọ̀nyí jáde.

### 3.1 Orin Ogun

A ti ṣo pé orin níí ṣíwájú ọ̀tẹ̀. Yàtọ̀ sí èyí, àwọn jagunjagun a máa ṣe àmúlò ọ̀pọ̀lọpọ̀ orin ìdẹ́rùbani láti fi ṣe àfihàn bí ọmọ ogun wọn ṣe pọ̀ tó èyí tí ọ̀tá kò níí le dúro dè àfi kí ó sálọ. Oríṣìíríṣìí ni àwọn órin yìí. Kódà a rí nínú àwọn jagunjagun Yorùbá tí ìtàn ṣọ pé fúnra wọn ni wọ́n máa ń lu ìlù ìṣẹ́gun lọ sí ogun. Lára àwọn orin tí àwọn ológun máa ń kọ lọ sójú ogun nìyí:

a. Múnimúni dé
Ará Ìbàdàn dé
Orò mọnigbénimì

b. Kò sẹ́ni tó lè dúró
À fòkè, à figbó

d. Lílé: Gídígbò gídígbò
Ègbè: E e yà
Lílé: Ẹ wí fálejò kó lọ
Ègbè: Ẹ fi ṣaṣara bàgbo

e. Bọ́wọ́ bá baláṣejù
Pípa ni ẹ pá
Ká rohun jẹ́ba lọ́la

ẹ. Orí mobà ní ó kun
Kòtò gìrìwò tó ń bẹ lÁkánrán
Orí móbà ní ó kun

Orin àkọ́kọ́ òkè yìí jẹ́ orin ìdẹ́rùbani torí àwọn ọ̀rọ̀ adẹrùbani tó wà nínú rẹ̀. Àwọn wọ̀nyí ni "Múnimúni" àti "Orò mọnigbénimì". "Múnimúni" gẹ́gẹ́ bí a ṣe lò ó nínú orin yìí ń tọ́ka sí "ẹni tí ó máa ń múni lẹ́rú". Òun náà ni a tún pè ní ará Ìbàdàn nínú ìlà kejì. Òun náà ni a pè ní "Orò mọnigbénimì". Òrìṣà ni Orò jẹ́. Kò sí ohun méjì tí Orò ń ṣe ju pé kí ó gbé ènìyàn lọ. Bí Orò bá gbé ẹnìkan, Orò pa onítọ̀hún ni. Orò yìí ni a fi pe ará Ìbàdàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tó jẹ́ pé mímọni rẹ̀ kò pé kó máṣe gbé ni mì. Pípe ará Ìbàdàn ní Orò níbí jẹ́ àfiwé ẹlẹlọ̀ọ́. Ìwà kan tí a fi wé ti Orò nínú ìwà ará Ìbàdàn níbí ni bí ó ṣe jẹ́ pé mímọni tí ará Ìbàdàn mọni kò sọ pé kí ó má ṣe múni lẹ́rú tàbí pani. Nínú orin kejì ni a ti sọ pé òkè àti igbó nìkan ni ó le dúró bí ó bá gbọ́ ìró ogun. Bí a ṣe sọ pé òkè nìkan ni ó le dúró nínú orin yìí jẹ́ ìfohunpènìyàn torí pé a fi àbùdá dídúró wọ òkè àti igbó bí ẹni pé ènìyàn ni wọ́n. Ẹ̀wẹ̀, òkè àti igbó tí ó tún le dúró de ogun níbí ni a tún le fi ojú àfidípò wo. Ohun tí òkè àti igbó le dúró fún nínú ìtumọ̀ ìjìnlẹ̀ orin yìí ni akọni ènìyàn tí kò le rí ogun sá gẹ́gẹ́ bí òkè àti igbó tí kì í sá fún ogun. Torí náà, ìkìlọ̀ ni orin yìí ń ṣe fún gbogbo ènìyàn tí kò bá rí bí òkè àti igbó láti tètè máa sá lọ torí pé ogun le mú wọn.

Nínú orin kẹta, ìpèdè ìdájàsílẹ̀ tí àwọn ọkùnrin tó tó ọkùnrin máa ń fi pilẹ̀ jàgídíjàgan ni "gídígbò gídígbò" jẹ́. Ìdáhùn tí àwọn elégbè dáhùn pé "E e yà" ń tọ́ka pé àwọn ti ṣe tán wàhálà náà. Èyí ló sì mú ẹni tí ó ń lé orin tún sọ pé, "Ẹ wí fáléjò kó lọ". Èyí ń tọ́ka pé kí ọmọ àlejò tí kò mojú ilẹ̀ tètè máa sálọ torí pé kò mojú ilẹ̀ bí ọmọ onílé. Àwọn elégbè sì tún dáhùn pé, "Ẹ fi ṣaṣara bàgbo". Ẹyọ ọwọ̀ ni Yorùbá tún ń pè ní ṣaṣará. Àwọn àgbo òògùn ìkà kan wà tó jẹ́ pé ṣaṣara ni wọ́n fí máa ń lò ó. Àpẹẹrẹ àwọn òògùn bẹ́ẹ̀ ni òògùn fífi oyin tani, dída ìgbóná sílẹ̀, ara títa tàbí òògùn ẹ̀fọ́jú. Torí náà, agbò tí àwọn elégbè ní kí wọ́n ki ṣaṣara bọ̀ jẹ́ àgbo òògùn ìkà tí Yorùbá fi ń jagun. Ìránnilétí òògùn lílò fún ọ̀tá ni orin yìí jẹ́. Orin kẹrin jẹ́ ìránnilétí ohun tí ó yẹ kí ọmọ ogun ṣe fún aláṣejù. Ohun tí orin yìí ní kí wọ́n ṣe fún aláṣejù ni pípa, kí wọ́n le rí ohun jẹ̀bà lọ́la. Ó yẹ kí á béèrè pé ṣe ẹ̀yà Yorùbá máa ń jẹ ènìyàn ni wọ́n fi sọ irúfẹ́ ìpèdè yìí. Èyí kò rí bẹ́ẹ̀, ohun tí wọn ń tọ́ka sí ni pé àwọn yóò pa aláṣejù bí wọ́n ṣe máa ń pa ẹran bí ewúrẹ́ tí wọ́n fi ń jẹun. Orin tí àwọn Àgbẹ́kọyà kọ ní inú ìjà owó orí ní ìlú Ìbàdàn àti àwọn agbègbè rẹ̀ ni orin karùn-ún yìí. A ó kíyè sí i pé àwọn jagunjagun Àgbẹ̀kọ̀yà sọ nínú orin yìí pé kòtò kan gìrìwò tí ń bẹ ní Àkánrán, orí àwọn ọlọ́pàá móbà tí àwọn bá pa ni yóó kún un. Kò rọrùn kí orí ènìyàn kún kòtò gìrìwò tó wà ní Àkárán, torí náà, àsọdùn lásán ni èyí. Ìdẹ́rùbọ̀tá lásán ni. Ṣùgbọ́n àwòrán tí ìlò èdè yìí ń yà sí wa lọ́kàn ni bí àwọn ènìyàn (móbà) tí wọn yóò pa yóó ṣe pọ̀ tó.

Ètè láti fi dẹ́rù ba ọ̀tá ni àwọn orin wọ̀nyí. Bí ọ̀tá tó bá lójo, tí kò gbáradì, tí kò múra sílẹ̀ dáradára bá gbọ́, yóò sálọ, kò sì níí dúró. Èyí yóò sì mú kíkẹ́rú àti kíkẹ́rù rọrùn fún àwọn tó gbé ogun náà wá ká wọn mọ́lé. Ọ̀kan lára oríṣìí ewì alohùn Yorùbá ni orin, bí a ṣe gbà lò ó lọ́gangan ipò yìí ló jẹ́ kí á mọ̀ pé ète ogun ni.

## 3.2 Bí Aṣawo Ṣe Lo Oríkì Eléńre Láti Fi Bẹ̀ Ẹ́ Nígbà Tí Àjùwọ̀n Àjàká Bẹ́ Orí Rẹ̀

Gẹ́gẹ́ bí Johnson (1921) ṣe sọ, Àjùwọ́n tí àlàjẹ́ rẹ̀ ń jẹ́ Àjàká ni Aláàfin tí ó jẹ lẹ̀yìn tí Ọ̀rànyàn gbésẹ̀. Oníwàtútù ni ọba yìí nígbà tí ó kọ́kọ́ dórí oyè. Èyí ló jẹ́ kí ọ̀ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ilù rí i fín, tí àwọn ogun Ìbàrìbá, Fúlàní àti Òwu kò sì jẹ́ kí Ọ̀yọ́ ó gbádùn. Báyìí ni àwọn Ọ̀yọ́ kọ̀ ọ́ tí wọ́n sì fi àbúrò rẹ̀ Aláàfin Ṣàngó jẹ. Lẹ́yìn tí Aláàfin Ṣàngó gbésẹ̀, Ọ̀yọ́ ráńṣẹ́ pe Àjàká látí wá padà jọba. Òun sì ni Aláàfin tí wọ́n tún fi jẹ lẹ̀yìn tí wọ́n ti rọ̀ ọ́ lóyè. Ìgbà ẹ̀ẹ̀kejì Àjàká yìí yàtọ̀ pátápátá torí pé ogun ló ń fi gbogbo ìgbà kó àwọn Ọ̀yọ́ lọ, èyí sì ni gbogbo ìlú fi gbà pé ọba tó burú jọjọ ni. Àjàká kó àwọn jagunjagun àti àwọn babaláwo tó gbówọ́ jọ, orúkọ Baṣọ̀run rẹ ni Ẹ́ẹ́rìndínlógún-àgbọn-kò-ṣé-dífá. Àwọn jagujagun Àjàká ni Olúgbọ́n, Arẹ̀sà, Oníkòyí àti Ajaguńlá. Àwọn babaláwo rẹ̀ sì ni Atagbọ́n-in, Àbìtìbítì Oníṣègùn, Pakú, Tẹ̀tẹ̀-ò-nírú, Yaanà, Ọkọ-àdán, Ẹ̀gbẹ̀gí, Àlàrí Baba Ìṣègùn àti Eléńre.

Nígbà tí àwọn babaláwo wọ̀nyí ti pẹ́ púpọ̀ ní ojú ogun, aáyun àwọn ìyàwó wọn ti yun wọ́n, wọ́n sì bá Àjàká sọ̀rọ̀ pé kó pa ogun tì. Torí ẹrú àti ẹrù Àjàká tí ó ń lé sí, àti pé kí àwọn babaláwo wọ̀nyí má baà ṣe tẹlòmíràn bí wọ́n bá dé ilé, Àjàká kò gbà pé kí wọn ó lọ. Àwọn náà jẹ́wọ́ fún un pé babaláwo ni àwọn. Atagbọ́n-in, Àbìtìbítì Oníṣègùn, Pakú, Tẹ̀tẹ̀-ò-nírú, Yaanà, Ọkọ-àdán, Ẹ̀gbẹ̀gí àti Àlàrí Baba Ìṣègùn bá bẹ̀rẹ̀ sí níí ṣubú lulẹ̀ lọ́kọ̀ọ̀kan tí wọ́n sì ń pòórá. Ó ku Eléńre nìkan. Àjàká ní kí òun náà ṣe bẹ́ẹ̀ tàbí kó pada sógun bí bẹ́ẹ̀ kọ́, òun yóó bẹ́ orí rẹ̀ fún Ògún. Eléńre kò dá a lóhùn, ó ń wo itú tí ọba fẹ́ pa. Àjàká pàṣẹ kí wọ́n bẹ́ orí aláìgbọràn náà. Gbogbo bí wọ́n ti ń gbìyànjú láti fi idà, àdá, ọ̀kọ̀, agada, òkúta ńlá pa Eléńre, pàbó ló já sí. Àjàká bá fi ọgbọ́n kún ọ̀rọ̀ náà, ó ti ara ìyàwó Eléńre (Ìjàẹ̀hìn) mọ àṣírí agbára rẹ̀, wọ́n sì lo fọ́nran bẹẹrẹ kan ṣoṣo láti fi bẹ́ orí Eléńre. Bí wọ́n ti bẹ́ orí yìí tán ni orí fò pọ̀n-ùn sí ọrùn ọwọ́ ọ̀tún ọba, ó sì di oríṣà tí kò jẹ́ kí ọba gbádùn. Gbogbo oúnjẹ tó yẹ kí ọba máa jẹ, ẹnu orí Eléńre ló ń bọ̀ sí. Ọba bá bẹ̀rẹ̀ sí níí ránṣẹ́ sí gbogbo àwọn babalàwo láti bá a lé orí náà kúrò ní ọrùn ọwọ́ rẹ̀. Gbogbo àwọn awo tó ń wá yìí ni kò rí orí náà lé kúrò. Nígbà tó yá, Àjàká ránṣẹ́ sí Aṣawo, tí i ṣe ọmọ Ayé, tó tẹ ìlú Ayétẹ̀ àti Ìdèrè dó. Ọlọgbọ́n ni awo yìí, ó ti gbọ́ ìròyìn wàhálà náà, bí ó sì ṣe yọ sí ààfin Àjàká, tí kò tilẹ̀ tí ì fojú kan Àjàká àti orí Eléńre ni a gbọ́ pé Aṣawo ti bẹ̀rẹ̀ sí níí ki oríkì Eléńre. Oríkì yìí náà sì ni ó tú u fó pé ó ti dé sí Ọ̀yọ́ Àjàká. Ó pọ́n ọn lé, ó sì rọ̀ ọ́ pé kó máṣe bínú. Lára

àwọn oríkì tí a gbọ́ pé Aṣawo ṣe àmúlò ni oríkì àwọn babaláwo gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹyọ nínú ewì ìsàlẹ̀ yìí.

Eléńre awo tó mọ dídá ọwọ́
Eléńre awo tó mọ ètìtẹ̀ alẹ̀
Eléńre awo tó mọ̀karara ẹbọ
Eléńre awo tí ì í parọ́
Eléńre awo tí ì í ṣèké
Eléńre awo tì í í ṣojo
Ò bá jèbùrẹ́ awo olùgbẹ́bẹ̀
Torí awo ní gbáwo nígbùn-únwọ́
Báwo ò gbáwo nígbùn-únwọ́
Awo a tẹ́ awo a ya...[1]

Bí a bá wo àwọn ìpèdè òkè yìí, ìlà mẹ́wàá ni ó ní. A le pín àwọn ìlà ewì yìí sí ọ̀nà méjì gbòòrò; abala oríkì (ìlà 1-6) àti abala ẹ̀bẹ̀ (ìlà 7-10). Nínú abala oríkì ni a ti ṣe àpọ́lé Eléńre nípa fífi gbólóhùn aláwìítúnwí ìhun gbé e kalẹ̀. A ṣe àwítúnwí orúkọ Eléńre níbẹ̀. Èyí tọ́ka sí i pé Eléńre ni òsùnsùn afọ̀ tí Aṣawo ń pè lemọ́lemọ́. Yorùbá nígbàgbọ́ nínú pípe ohun kan lemọ́lemọ́. Èyí sì ni ìdí tí a fi máa ń ṣe àwítúnwí orúkọ àwọn ẹ̀mí àìrí tí apọfọ̀ fẹ́ kó rọ̀ wá ran òun lọ́wọ́. Bákan náà, Yorùbá gbà pé gbọmọgbọmọ ni à ń ránfá adìtí. Kì í ṣe pé Eléńre dití ṣùgbọ́n ó kọtí ọ̀gbọnhin sí àwọn babaláwo tí Àjàká ti pè ṣáájú. Èyí ló fa dídárúkọ rẹ̀ léraléra gẹ́gẹ́ bí Aṣawo ti ṣe yìí. Ìdáláre tún wà bí a bá tún abala oríkì yìí pín sí méjì bí a bá lo bí àwọn gbólóhùn inú abala náà ṣe bá ara wọn dọ́gba gẹ́gẹ́ bí òṣùwọ̀n. Abala àkọ́kọ́ nínú abala oríkì yìí ni ìlà kìn-ín-ní sí ìkẹta (ìlà 1-3). Àwọn gbólóhùn inú abala yìí bá ara wọn dọ́gba nínú ìhun, èyí sì jẹ́ kó rọrùn fún “dídá ọwọ́”, “ètìtẹ̀ alẹ̀” àti “ìkara ẹbọ” láti bá ara wọn rìn. A tún le rí “dídá ọwọ́”, “ètìtẹ̀ alẹ̀” àti “ìkara ẹbọ” gẹ́gẹ́ bí òṣùwọ̀n pàtàkì láti ṣe ìgbéléwọ̀n babaláwo ojúlówó. Bákan náà, “tí ó” (tó) inú àwọn ìpèdè yìí jẹ́ atọ́ka gbólóhùn ìjọ́hẹn tí ó máa ń fi òtítọ́ inú gbólóhùn (ọfọ̀) tí kò le di irọ́ láéláé hàn. A ṣe àmúlò àbùdá yìí láti ṣe àyẹ́sí Eléńre nínú àwọn ìpèdè òkè náà ni. Gbogbo ìwọ̀nyí ń tọ́ka pé ojúlówó awo tó gbọ́ Ifá dójú àmì ni Eléńre. Èyí sì jẹ́ àpọ́nlé fún un.

Apè àpọ́nlé yìí náà ni aṣafọ̀ so mọ́ abala kejì nípa àbùdá àti ìtumọ̀ rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi òtítọ́ nípa Eléńre hàn nínú ìpedè inú àtúnpín àkọ́kọ́ abala kìn-ín-ní nípa lílo atọ́ka gbólóhùn ìjọ́hẹn náà ni a ṣe fi òtítọ́ nípa rẹ̀ hàn nínú abala kejì yìí nípa lílo atọ́ka gbólóhùn àyísódì (“ì í” tó jẹ́ àgékúrú “kì í”). A ṣe àwítúnwí ìhun gbólohùn (#Awo tí kì í .......#[2] ) náà níbí. Èyí jẹ́ kí àwọn “pa”, “ṣe” àti “ṣe”

1 Johnson (1921) kò sọ pàtó oríkì tàbí ìpèdè ẹ̀bẹ̀ tí Aṣawo ṣe àmúlò. Èyí ló mu wa béèrè ọ̀rọ̀ lọ́wọ́ Bàbá Fágbénlé Awólọ́wọ̀ tó jẹ́ ọmọ ìlú Ayétẹ̀, ẹni tí a gba ohùn yìí lẹ́nu rẹ̀.

2 Àmì “#” yìí dúró fún ìbẹ̀rẹ̀ àti ìparí gbólóhùn.

bá ara wọn rìn. Bákan náà ni "irọ́", "èké" àti "ojo" náà bá ara wọn rìn. Ìwà burúkú tí Eléṅre kò ní tí kò sì le pada ní láéláé ni àwọn gbólóhùn yìí fi hàn.

Abala kejì ni Aṣawo ti bẹ Eléṅre pé kó jèbùrẹ́ awo olùgbẹ́bẹ̀. "Jẹ èbùrẹ́ awo olùgbẹ́bẹ̀" jẹ́ ìpedè kan tó gbajúmọ̀ láàárín àwọn babaláwo láti fi bẹ ara wọn. Èyí fi hàn pé ẹ̀bẹ̀ ni ìpèdè náà dúró fún. Aṣawo kò tún dákẹ́ bí ó ṣe pa òwe pé "... awo níí gbáwo nígbọ̀wọ́, bí awo ò gbáwo nígbọ̀wọ́, awo a tẹ́, awo a ya". Ohun tí Aṣawo sọ níbí ni pé awo ni olùrànlọ́wọ́ awo tí awo fi í ṣe àṣeyọrí àti pé bí awo kò bá ran awo lọ́wọ́, awo kò le ṣe àṣeyọrí. Ohun tí èyí ń tọ́ka sí ni pé Àṣeyọrí Aṣawo wà lọ́wọ́ Eléṅre.

Torí àwọn ìpẹ̀ tó ṣe yìí, Eléṅre gba ìpẹ̀ rẹ. Ó tijú rẹ̀ torí pé kàkà kó sàágùn bíì àwọn awo ìṣáájú, àyẹ́sí rẹ̀ ló ṣe. Eléṅre náà sì mọ̀ pé bí ó ṣe jẹ́ pé ọmọ àlè ní ó máa ń rínú tí kì í bí náà ni ó jẹ́ pé ọmọ àlè ni a máa ń bẹ̀ tí kì í gbà. Bí ẹlẹ́jọ́ bá sì ti mọ ẹjọ́ rẹ̀ lẹ́bi, kì í pẹ̀ lórí ìkúnlẹ̀ mọ́. Orí Eléṅre fò kúrò lọ́wọ́ Àjàká, ó sì di odò Eléṅre tó ń ṣàn ní Ọ̀yọ́ Àjàká. Ìyàwó rẹ rí i pé òun ti dalẹ̀ ọkọ òun, òun náà sì di odò ṣùgbọ́n Eléṅre fi í bú pé kò níí le ṣàn títí ayé.

Kókó ohun tí a fẹ́ láti fà yọ nínú ìtàn yìí ni pé, ogun tí àwọn awo tó wá ṣíwájú Aṣawo kò rí ṣẹ́ nípa lílo òògun, àdá, ọ̀kọ̀, ààké, ọfà, èlè àti àwọn nǹkan ìjagún mìíràn ni Aṣawo fi ète ewì (nípa lílo oríkì) ṣẹ́. Ẹ̀yà kan tó nífẹ̀ẹ́ orúkọ wọn dọ́ba ni Yorùbá, wọn a sì máá fẹ́ gbọ́ ohùn ẹni tó máa ń ṣàyẹ́sí wọn. Èyí ló jẹ́ kó rọrùn fún Aṣawo láti le ṣàṣeyọrí nínú lílo ètè náà gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe lò ó yìí.

### 3.3 Ìtàn Ọkùnrin Kan Tí Ìyàwó Rẹ̀ Gbà Là

Nínú Ọdúnjọ (1971), ìtàn àtẹnudẹ́nu nípa arákùnrin kan tí kò ní ìgboyà jẹyọ níbẹ̀. Arákùnrin yìí ni òun àti ìyàwó rẹ̀ dìjọ ń rin ìrìnàjò láti lọ ṣòwò. Àsìkò yìí ní ilẹ̀ Yorùbá jẹ́ àsìkò tí àwọn agbésùnmọ̀mí ń gbé sùnmọ̀mí kiri, tí wọ́n ń dá àwọn ènìyàn lọ́nà, tí wọ́n ń kó wọn lẹ́rù, tí wọ́n sì tún ń kó wọn lẹ́ru. Kí ìrìn àjò wọn le já sí ìrọ̀rùn ni ọkọ obìnrin yìí fi múra ogun àti òògùn kúrò nílé. Nígbà tó yá nínú ìrìn àjò wọn, àwọn agbésùnmọ̀mí kan dá wọn lọ́nà. Sí ìyàlẹ́nu aya ọkùnrin yìí, ọkọ rẹ̀ tó ti rò pé gbogbo òògùn tó dì mọ́ra ti tó o láti bá àwọn agbésùnmọ̀mí náà jà, kí ó sì ṣẹ́gun wọn bá bẹ̀rẹ̀ sí níí gbọ̀n pẹ̀pẹ̀ torí ojòra àti ẹ̀rù tó bà á. Bí ìyàwó ṣe rí ọkọ rẹ̀ báyìí, ó yanú kótó, ó sì bẹ̀rẹ̀ sí níí sọ pé:

> Máa gbọ̀n
> Máa gbọ̀n
> Ọkọ mi máa gbọ̀n
> Bóo ti ń gbọ̀n tóo fi ń pogún
> Bóo ti ń gbọ̀n tóo fi ń pọgbọ̀n
> Olówó orí mi ọkọ mi sá máa gbọ̀n bẹ́ẹ̀

Bí àwọn agbésùnmọ̀mí náà ṣe gbọ́ báyìí ṣe ni wọ́n dúró lójìjì, wọ́n sì sá wọgbó lọ. Èrò wọn ni pé níbi gbígbọ̀n tí ọkùnrin náà ń gbọn ni agbára rẹ̀ wà, pé ó ṣẹ̀ṣẹ̀ fẹ́ máa ja òògùn ni àti pé inú ti bí i kọjá ààlà ni ó ṣe ń gbọ̀n pẹ̀pẹ̀ bẹ́ẹ̀. Ohun tí a fẹ́ láti tọ́ka sí níbí ni pé nípa ète àmúlò èdè ewì ni obìnrin inú ìtàn yìí ṣe ṣẹ́ ogun tí kò bá ja òun àti ọkọ rẹ̀, tí kò bá sì kó wọn lẹ́rù àti ẹrú.

Bí a bá ṣe àgbéyẹ̀wò ìlò èdè inú àyọlò yìí, arábìnrin yìí ṣe àwítúnwí àwọn gbólóhùn “Máa gbọ̀n”, èyí ń tọ́ka rẹ̀ pé gbígbọ̀n yìí gan-an ni aṣàfọ̀ fẹ́ kí òsùnsùn afọ̀ rẹ̀ tẹ̀ síwájú láti máa ṣe. Nípa báyìí ni ogun yóó fi ṣẹ́. “Ọkọ mi” tí aṣafọ̀ sọ yìí jẹ́ kí á mọ ẹni tí ó dojú ọ̀rọ̀ kọ ní pató. Èyí sì fi hàn bí ẹni pé ìyàwó náà ti mọ ìṣesí ọkọ rẹ̀ tẹ́lẹ̀. Èyí ni aṣafọ̀ fi hàn nígbà tí ó tẹ̀ síwájú pé “Bóo ti ń gbọ̀n tóo fi ń pogun” àti “Bóo ti ń gbọ̀n tóo fi ń pọgbọ̀n”. Àwọn gbólóhùn yìí jẹ́ gbólóhùn adọ́gba. Èyí sì jẹ́ kí aṣafọ̀ le sọ ìrírí rẹ̀ nípa òsùnsùn afọ̀ nígbà tí ó bá ń gbọ̀n. Ohun tí “ogún” àtì “ọgbọ̀n” ń tọ́ka sí nínú gbólóhùn wọ̀nyí ni “èniyàn ogun ” àti “èniyàn ọgbọ̀n”. Àwọn ọ̀rọ̀ méjèèjì náà jẹ́ àjùmọ̀rìn ọ̀rọ̀. Nígbà mìíràn a le tọ́ka “ogún” àti “ọgbọ̀n” bí a bá fi ń ka èniyàn gẹ́gẹ́ bí i ìlọ́po “lógúnlógún” àti “lọ́gbọ̀nlọ́gbọ̀n”. Bí èyí bá rí bẹ́ẹ̀, òǹkà èniyàn tí a ní lọ́kan le má mọ ní ogún tàbí ọgbọ̀n nìkan bí kò ṣe ìlọ́pò èniyàn ní òǹkà ogun àti ọgbọ̀n. Ní pàtó, àwòrán ọ̀pọ̀ èniyàn ní “ogún” àti “ọgbọ́n” ń yà síni lọ́kàn. Èyí sì ni ìdí pàtàkì tí àwọn agbésùnmọ̀mí náà fi sálọ kí ọkùnrin yìí má baà fi gbígbọ̀n rẹ̀ pa wọ́n tán láàárín ìṣẹ́jú àáyá.

### 3.4 Lílo Èdè Àyàn Láti Fi Tan Kúrunmí Nínú Ogun Ìjàyè Àti Ìbàdàn

Ìtàn mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ nípa ogun Ìjàyè ni a sọ níbí. Àkọ́kọ́ jẹ́ ti Johnson (1921), èkejì ni ti Abíọ́dún (2013), ẹ̀kẹta ni ti Adébóyè Onígbìndé. Torí pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn wọ̀nyí gbẹ́nu léra, níṣe ni a ó máa ti inú ìtàn kan bọ́ sí inú èkejì àti láti inú èkejì bọ́ sínú ẹ̀kẹta. Ogun Ìjàyè jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ìtàn ogun tí ó fi lílo ewì gẹ́gẹ́ bí ète ogun jíjà múlẹ̀. Ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn ogun mánigbàgbé ní ilẹ̀ Yorùbá lápapọ̀ ni ogun yìí jẹ́. Ogun yìí náà ni Johnson (1921) pè ni ogun Bátẹ̀dó. Johnson tún ṣe àlàyé pé lára ohun tó dá wàhálà sílẹ̀ ni bí Iba Olúyọ̀lé ti ṣe ń rò pé ó yẹ kí ipò òun sún mọ́ ti Aláàfin. Ohùn ìlù rẹ̀ tí àwọn onílù máa ń lù fún fi èyí hàn. Bí àwọn onílù rẹ̀ bá ń kì í, wọn á máa wí pé:

> “Ìba kúkú jọba,
> Má ṣe bí ọba mọ́”
>
> (Johnson 1921:279)

Ewì (èdè àyàn) yìí fi hàn pé Iba ti ń ṣe bí ọba tẹ́lẹ̀. Atọ́batẹ́lẹ̀ ni, kò sí ohun tí a le rí lára ọba tí a kò le rí lára rẹ̀. Lótìítọ́ kì í ṣe pé ipò ọba kò wù ú ṣùgbọ́n ọmọ obìrin ló jẹ́ sí Aláàfin. Èyí kò sì le jẹ́ kó ṣe é ṣé fún un láti jọba. Báyìí ló bẹ̀rẹ̀ sí níí ta Àārẹ Kúrunmí lẹ́nu. Kúrunmí tó jẹ́ Àārẹ-Ọ̀nà Kakaǹfò ilẹ̀ Yorùbá nígbà náà ni ipò rẹ̀ sún mọ́ ti ọba. Ipò yìí kò sì ní ìran. Iba Olúyọ̀lé

náà le jẹ ẹ́. Ogun Ìjàyè bẹ̀rẹ̀ nígbà tí Ààrẹ lé Aṣú (Ààrẹ Ládìgbòlù) olóyè kan kúrò ní Ìjàyè lọ sí Fìdítì. Aṣú gba àwọn ọ̀tá Ààrẹ gẹ́gẹ́ bí olùgbọ̀wọ́. O lọ̀dí àpò pọ̀ mọ́ Iba, Iba sì fi Bálógun Ọdẹ́rìnlọ àti Ìbíkúnlé ránṣẹ́ láti lọ ran Aṣú lọ́wọ́. Gẹ́gẹ́ bí àlàyé Johnson (1921), ogun yìí kò rọrùn fún àwọn ọmọ ogun Ìbàdàn torí pé ogun Ààrẹ-Ọ̀nà Kakaǹfò fẹ́rẹ̀ pa gbogbo wọn tán. Kódà bí kì í bá ṣe pé Ìbíkúnlé tó jẹ́ Sérikí ogun Ìbàdàn nígbà náà bọ́ sọ́wọ́ àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ láti Ìjàyè ni, kò bá bá ogun lọ. Ohun mìíràn tó tún ran àwọn ogun Ìbàdàn lọ́wọ́ ni pé ilẹ̀ ṣú bá wọn lẹ́nu ogun yìí, nígbà tí ilẹ̀ ṣú, ikú oró tí kò bá pa gbogbo ọmọ ogun Ìbàdàn rún dáwọ́ dúró. Ìdí níyì tí wọ́n fi pe ìjà àkọ́kọ́ láàrin Ìbàdàn àti Ìjàyè náà ni ogun "Òrugbàmílà". Ogun Ìbàdàn túnra mú, wọ́n ránṣẹ́ sí àwọn jagunjagun Ẹ̀gbá bíí Ṣódẹkẹ́, Àpati, Ànàbá, Olúfakùn, Ṣómóyè àti Ògúnbọ̀nà fún ìranlọ́wọ́. Johnson (1921) fi kun pé nígbà tí Aláàfin sọ ọ̀rọ̀ ìjà yìí tì ló bá pàṣẹ pé kí wọ́n gẹ̀gun Ṣàngó lọ sí ogun náà, èyí fi hàn pé bí ọba ayé kò bá le sọ ọ́ kó parí, ó yẹ kí ọba ọ̀run le parí rẹ̀. Nígbà yìí ni ogun náà tó rọlẹ̀.

Abíọ́dún (2013) ṣe àlàyé pé alàgbà Láyíwọlá Adìó, ọ̀kan lára àwọn àgbà ilé Kúrunmí ní Ìjàyè fi yé òun pé, ọba tí Adélú jẹ lẹ́yìn ikú baba rẹ̀ (Àtibà) ló fa ìjà ogun Ìjàyè. Kúrunmí fara mọ́ ogun ju yíyanjú ọ̀rọ̀ náà ní ìtùbí-ìnùbí lọ. Ìbàdàn tó jẹ́ ọ̀tá Kúrunmí gbè lẹ́yìn Adélú, bákan náà ni àwọn ilẹ̀ Yorùbá mìíràn tó tó mẹ́rìnlélógóje níye ṣe. Báyìí ni àwọn àpapọ̀ ogun náà dojú ogun Ààrẹ bolẹ̀. Ṣùgbọ́n kí wọ́n tó rí èyí ṣe, Ààrẹ Kúrunmí ti fi ìgbà kan mú Baṣọ̀run Ògúnmọ́lá lẹ́rú tó sì jẹ́ pé eerú ni ó ń fún un lá. Ìdí nìyí tí wọ́n fi ń ki Ogúnmọ́lá ní "ọmọ aléérúmákùú". Alàgbà Láyíwọlá Adìó fi kún àlàyé rẹ̀ pé gbogbo ìlú Ìjàyè ni ogun Ogúnmọ́lá jẹ run gúdúgúdú, ìdí nìyí tí wọ́n fi ń pa á lówe pé, "Ọ̀pẹ Ìjàyè ló le ròyìn ogun Ògúnmọ́lá" Etí odò Ọ̀sẹ̀ ni ogun ká Kúrunmí mọ́, ibẹ̀ ni ogun sì ti mú un lọ.

Oloyè Adébòyè Onígbíndé[3], ṣàlàyé pé "ète ìlù" ni ogun Ìbàdàn fi ṣẹ́gun Kúrunmí létí odò Ọ̀sẹ̀. Ó ní nígbà tí ogun náà kọjá sísọ fún àwọn igun méjèèjì ni kálukú ti sọ àwọn ọmọ ogun àti àwọn onílù rẹ̀ nù. Onígbíndé tẹ̀ siwájú pé Ògúnmọ́lá ni ó kọ́kọ́ ṣe àwárí àwọn onílù rẹ̀ lókè odò. Lẹ́sẹ̀ kan náà ló kó àwọn ọmọ ogun jọ, ó ní kí wọ́n fara pamọ́, ó sì pàṣẹ pé kí àwọn onílù òun ó yíwọ́ ìlù wọn po sí ti Kúrunmí. Gẹ́gẹ́ bí Onígbíndé ti ṣe sọ, Kúrunmí tó wà nísàlẹ̀ odò gbọ́ ìró ọwọ́ ìlù rẹ̀ bí ó ti ń dún pé:

Ìjà orogún ò wọ̀
Orogún
Ìjà orogún ò wọ̀
Orogún

3 Ẹni tí ó ti fi ìgbà kan jẹ́ akọ́nimọ̀-ọ̀ngbà fún àwọn ẹgbẹ́ agbábọ́ọ̀lù àgbà-Ọ̀jẹ̀ ilẹ̀ Nàìjíríà (Super Eagle) sọ èyí nibi ayẹyẹ ọdún ìlù (*Drum Festival*) ti ọdún 2012 ní ọgbà Yunifátìtì Ìbàdàn.

Ìjà orogún ò wọ̀
Orogún...

Kúrunmí rò pé àwọn ènìyàn òun ti gòkè odò, ó sì fi bẹ̀ẹ̀ bọ́ sí ààrin ọ̀tá. Kò sí ìrànlọ́wọ́ kankan fún un torí pé ààrín àwọn ọ̀tá ló bọ́ sí, báyìí ni ó bógun lọ. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ lókè, a ó rí i pé èdè àyàn (èwì) tí a fi ki oríkì rẹ̀ ni okùnfà pàtàkì tó pilẹ̀ ogun yìí, òhun náà sì tún ni ète pàtàkì tí ọmọ ogun Ògúnmọ́lá lò láti fi ṣẹ́gun Kúrunmí, odidi Ààrẹ-Ọ̀nà Kakaǹfò ilẹ̀ Yorùbá. Ohun tí ó jẹ́ kí ète yìí mú un ni bí ó ṣe gbáralé èdè àyàn tí ó jẹ́ ohun ìdámọ̀ rẹ̀ lójú ogun. Àṣà fífi ohun ìlù dáni mọ̀ tàbí sọ ibi tí a wà yìí wọ́pọ̀ láarin àwọn jagunjagun ayé àtijọ́.

A le rí “orogún” tí a ṣe àwítúnwí rẹ̀ yìí gẹ́gẹ́ bí ègbè èdè àyàn náà. Ìdí ni pé àwọn onílù tó lu ìlù yìí pé méjì, mẹ́ta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ torí pé wọ́n jẹ́ onílù ogun nínú èyí tí a ti gbọ́dọ̀ rí olómele àti alùyá ìlù. Ohun tí “Ìjà orogún ò wọ̀” ń tọ́ka sí ni pé, ìjà orogún máa ń le, ó sì kún fún oríṣìíríṣìí ète. Yorùbá a tilẹ̀ máa pa á lówe pé, “Ríro ló ro ni a fi pè é ní orogún, kíkan lo kan la fi pè é ní ọbàkan”. Bí èyí bá rí bẹ́ẹ̀, ó yẹ kí á le ṣe ìbéèrè pé ṣél Kúrunmí tó jẹ́ olórí ogun ilẹ̀ Yorùbá kò mọ̀ tẹ́lẹ̀ pé wọ́n le dẹ irúfẹ́ okùn bẹ́ẹ̀ fún òun ni? Ìdáhùn sí èyí ni pé “A kì í gbọ́n bí ẹni tó ń ṣọ́ ni”, àti pé “Bí sẹ̀ría bá fẹ́ láti dá àjànnàkú, fọ́nrán òwú kan a máa gbé e dè”. Kì í ṣe pé a fẹ́ láti fi Kúrunmí hàn gẹ́gẹ́ ẹni Ibi, ohun tí a fẹ́ tọ́ka sí ni pé kò sí ẹni tí ète ọ̀tá kò le mú.

### 3.5 Àmúlò Òòṣà-Èrò (òkúta) Láti Fi Ṣẹ́gun Fúlàní Adigunjalè Ní Igbó-Ọrà Látijọ́

Olóyè Wahabi Láwànì Àyísá[4], ṣàlàyé pé lẹ́yìn ogun Ìdàhọ́mì, tí àwọn ènìyàn ìlú Igbó-Ọrà rò pé ogun ti tán ni ògbólógbòó fúlàní adigunjalè kan tún bẹ̀rẹ̀ sí níí yọ Ìgbó-Ọrà lẹ́nu. Fúlàní yìí a máa ti agbègbè ìgbèríko Abẹ́òkúta wá. Gbogbo agbára ni àwọn jagunjagun àsìkò náà sà láti kápá olè yìí ṣùgbọ́n wọn kò rí i gbé ṣe. Ó ṣe ní ọjọ́ kan, àwọn ìlú gbọ́ pé olè náa tún ń bọ̀ wá, wọ́n sì ti múra ọgbọ́n tí wọ́n yóò lò fi bá a jagun. Bí ó ti dé tó ń bá àwọn jagunjagun yìí jà lọ́wọ̀ bí ti í máá ṣe, wọ́n ṣá a lọ́gbẹ́ kò ràn án, wọ́n ta á lọ́fà kò rí i gbé ṣe, wọ́n dìgbò lù ú kò balẹ̀ bẹ́ẹ̀ sì ni òògùn ò ràn án. Àwọn jagujagun yìí ti fẹ́ máa sá lọ tí kò sì sẹ́ni tó rántí ète mìíràn tí wọ́n pa kalẹ̀ dè é mọ́. Olóyè Wahabi Àyísá tẹ̀ síwájú pé ṣàdédé ni ẹ̀nìkan nínú wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí níí kọrin, tí àwọn yòókù sì ń bá a gbè é pé:

| | |
|---|---|
| Lílé: | Ẹnìkan kì í róògùn òòṣà-èrò ṣe |
| Ègbè: | Òòṣà-èrò |

4 Ìkọ́làbà ìlú Igbó-Ọrà tó gbésẹ̀ ló ṣọ èyí lásìkò tí mò ń ṣe akitiyàn láti kó àwọn ìtàn tó jọni lójú nípa ìlú Igbó-Ọrà jọ.

Lílé: Ẹnìkan kì í róògùn òòṣà-èrò ṣe
Ègbè: Òòṣà-èrò...

Lọ́gán tí èyí ṣẹlẹ̀, àwọn jagunjagun náà rántí ète tí wọ́n ti pa kalẹ̀, kálukú sì bẹ̀rẹ̀ sí níí sọ àwọn òketè òkúta tí wọ́n ti pèsè kalẹ̀ bá ọlọ́ṣà yìí. Òtítọ́ ni adigunjalè yìí ní òògùn oríṣìíríṣìí ṣùgbọ́n kò múra tòkúta lọ́wọ́. Kò sì lérò pé wọ́n le ja irúfẹ́ ìjà ìjàǹbá bẹ́ẹ̀. Bí wọ́n ṣe fi òkúta tí ọ̀kọrin náà fi orin rẹ̀ rán wọn létí ṣẹ́gun nìyí.

A fẹ́ ká kíyè sí i wí pé ẹni tó rán wọn letí ète yìí kò pe ète náà ní orúkọ tí gbogbo èèyàn mọ̀ ọ́n sí, dípò bẹ́ẹ̀, ó pè é ni orúkọ tó jẹ́ pé bí ènìyàn kò bá gbọ́ èdè Yorùbá dunjú, kò le mọ ìtumọ̀ rẹ̀, ṣé Fúlàní sì kúkú ni ẹni tí wọn ń bá jà, kò gbọ́ èdè Yorùbá púpọ̀. Ohun tí ọ̀kọrin ṣe àmúlò níbí ni lílo èdè àdàpè láti fi da nǹkan rú mọ́ ọ̀tá lójú. A tún le pe àmúlò "òòṣà èrò" níbí yìí ní ẹnà, tí ọmọdé tàbí àjèjì/aláìgbédè, tí kò mọ àṣà àti èdè àwùjọ dunjú kò le gbọ́. Ká ní òkúta ni akéwì pè é ni, bóyá kò bá funra, kí ó sì túnra mú tàbí kó kúkú máa sálọ. Báyìí ni akéwì náà ṣe ṣe olùgbàlà ìlú Igbo-Ọrà nípa lílo ète ewì láti fi rán wọn létí ọ̀nà ẹ̀bùrú tí wọ́n fẹ́ báyọ sí ogun olè tó ń jà wọ́n náà.

A tilẹ̀ tún gbọ́ pé lọ́gán tí ọwọ́ ba ọkùnrin yìí ni ère tí ìyàwọ rẹ̀ máa ń fún lọ́yàn kí ó ba à le ṣẹ́gun kò gba ọmú mọ́. Ṣé ó kúkú máa ń mọ ìlú tí ọkọ rẹ̀ bá ń lọ jà lólè, ó forí lé ibẹ̀, ó sì ń pariwo pé

Àwòrán ò mọ̀mọ́
Bàbá gbàmí
Àwòrán ò mọ̀mọ́
Ìyá gbàmí
Àwòrán ò mọ̀mọ́
Ará ilé gbà mí
Àwòrán ò mọ̀mọ́
Èrò ọ̀nà gbà mí
Àwòrán ò mọ̀mọ́[5]

Ohun tí ó ń sọ ni pé àwòrán (ère) agbára ọkọ òun kò gba ọyàn mọ́, kí wọ́n jọ̀wọ́ má pa ọkọ òun. Ère ni ó pè ní "àwòrán", "kò mu ọmú" sì ní ó fẹ́ wí tí ó fi sọ pé "kò mọ̀mọ́". Èyí túnbọ̀ fi hàn pé aláìgbédè ni tọkọtaya ọlọ́ṣà náà, àìgbédè Yorùbá dáradára wọn sì kún inú ohun tó ṣekú pa wọ́n. Báyìí ni wọ́n ṣe irú ìdájọ́ tí wọ́n ṣe fún ọkọ rẹ̀ fún un; wọ́n pa á pẹ̀lú òkúta.

5 Orin yìí jẹ́ èyí tí a gbọ́ lẹ́nu Olóyè Wahabi Àyísá bákan náà.

## 3.6 Ìja Ẹ̀sìn Láàárin Àwọn Ọmọ Ìṣòrò àti Àlùfáà Kamar-ud-deen ní Ìlú Ìgbó-Ọrà Lọ́dún 1993

Ìtàn ajẹmógun mìíràn tó tún fìdí èrò pé ewì jẹ́ ète ogun jíjà múlẹ̀ ni ìja ẹ̀sìn láàárin àwọn ọmọ ìṣòrò àti àlùfáà Kamar-ud-deen ní ìlú Ìgbó-Ọrà ní oṣù keji, ọdún 1993. Ó ṣojú mi kòró ni ìṣẹ̀lẹ̀ tí ń ó sọ yìí. Ọdún orò ni ìlú Igbo-Ọrà ní oṣù kejìlá, ọdún 1993 wáyé bí ogun ni. Lọ́wọ́ òwúrọ̀ kùtùkùtù ọjọ́ àháṣúlẹ̀/ ìséde/ìkìje orò tí àwọn eégúnrò mẹ́rin ìlú Igbó-Ọrà máa ń jádé, àwọn eégúnrò náà ni Lájọrun, Láṣọgbà, Lágayè àti Ògbojà, òkìkí ṣàdéédé kàn pé alùfáà Kamar-ud-deen ti kó àwọn obìnrin dé ọjà Igbo-Ọrà. Gbogbo ènìyàn, yàtọ̀ sáwọn obìnrin ló lọ wòran ìṣẹ̀lẹ̀ náà. Bí àlùfáà yìí ṣe dé, iwájú mọ́ṣáláṣí ọjà ló duró sí àti àwọn ẹlẹ́háá rẹ̀. Wọ́n ń kọrin àsàláátù lóríṣiíríṣìí, wọ́n sì ń lu ìlù bẹ̀nbẹ́ àsàlátù sí i. Gbogbo wọn ń jó. Kó pẹ́ sí ìgbà yìí ni Lájọrun ń ti igbórò rẹ̀ bọ̀. Ó ti wà nínú eégúnrò, ṣé òkìkí ti kàn bá a tẹ́lẹ̀, ó bá wọn lótìítọ́, ó bá bẹ̀rẹ̀ sí níí pa itú méjeméje fún wọn. Sí ìyàlẹ́nu gbogbo ènìyàn, ọ̀kankan nínú àwọn ọ̀pọ̀lọpọ̀ obinrin wọ̀nyí kò kú. Lẹ́nu èyí ni gbogbo àwọn orò yòókù bá wọn, gbogbo wọn ló pa itú ṣùgbọ̀n bákan náà lọ̀rọ̀ rí. Àwọn ènìyàn tó wà níbẹ̀ rí èyí sí ìyàlẹ̀nu, kálukú sì káwọ́ gbera. Ká ni àkókò yìí ni àlùfáà yìí bá kó àwọn ènìyàn rẹ̀ sọ́kọ̀ tó forí lé ọ̀nà Abẹ́òkúta tó bá wá kò bá yẹ ẹ́, ṣùgbọ́n kò ṣe bẹ́ẹ̀. Àwọn ọmọ ìlú ka èyí sí ìwọ̀sí ńlá àti ìgbésẹ̀ láti pa orò ọdún run. Lọ́gán ni orin kan sọ láàárin àwọn òǹwòran pé:

| | |
|---|---|
| Lílé: | Bóògùn ò ràn wọ́n ò<br>Ẹ kógi bò wọ́n o<br>Bóògùn ò ràn wọ́n<br>Ẹ kógi bò wọ́n o<br>Bó bá ṣe póbinrin ni ó borò jẹ́ o |
| Ègbè: | Bóògùn ò ràn wọ́n<br>Ẹ kógi bò wọ́n o |
| Lílé: | Bó bá ṣe póbinrin ni ó borò jẹ́ o |
| Ègbè: | Bóògùn ò ràn wọ́n<br>Ẹ kógi bò wọ́n o |

Lẹ́sẹ̀ kan náà ni àwọn ènìyàn bẹ́rẹ̀ sí níí ju òkò, igi, páléke, eegun ẹran àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ lu àwọn ìjọ wọ́nyí. Lójú ẹsẹ̀ ni ẹ̀jẹ̀ ti bo àwọn ẹlẹ́háá náà, wọ́n ṣe àwọn ọkùnrin wọn bọ́ṣẹ́ ṣe ń ṣojú, wọ́n ba gíláàsì àwọn ọkọ̀ wọn jẹ́, wọ́n sì ṣetán láti pa gbogbo wọn. Àwọn ọlọ́pàá tó wà ni ibi ìṣẹ̀lẹ̀ yìí kò gba èyí láyè, wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí níí yin ìbọn tajútajú, wọ́n sì le gbogbo ènìyàn kúrò láti fi dóòlà ẹ̀mí àwọn ènìyàn yìí.

Bí a bá wo orin yìí, kókó ohun tí ọ̀kọrin náà fẹ́ kí àwọn ènìyàn tó fẹ́ láti gbèjà ìlú wọn ṣe ni ó kọ́kọ́ ṣe àwítúnwí rẹ̀ ní ẹ̀ẹ̀mejì bí ó ṣe sọ pé “Bóògùn ò ràn wọ́n ò; Ẹ kógi bòwọ́n o” ní kí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ tó wá sọ pé “Bó bá ṣe póbinrin ni

ó borò jẹ́ o". Láti fi hàn pé ohun tí ọ̀kọrin náà sọ yé àwọn, ohun tó fẹ́ kí wọ́n ṣe "Bóògùn ò ràn wọ́n; Ẹ kógi bò wọ́n o" tó sọ ní ẹ̀ẹ̀mejì yìí náà ni àwọn náà fi gbe orin yìí. Ohun tí ó ṣẹlẹ̀ níbí ni pé ọ̀kọrin mọ̀-ọ́nmọ̀ yí ìhun gbólóhùn orin yìí padà torí kí ó le tẹnu mọ́ "Ẹ kógi bò wọ́n o" tí ó fẹ́ kí wọ́n ṣe ni. Bí ó ṣe yẹ kí ihun orin yìí jẹ́ ni:

Lílé: Bó bá ṣe póbinrin ni ó borò jẹ́ o
Bóògùn ò ràn wọ́n
Ẹ kógi bò wọ́n o
Ègbè: Bó bá ṣe póbinrin ni ó borò jẹ́ o
Bóògùn ò ràn wọ́n
Ẹ kógi bò wọ́n o

Orin náà á wá jẹ́ àjùmọ̀kọ tàbí kí ó jẹ́ pé gbólóhùn tí ọ̀kọrin fi lé orin náà ni àwọn elégbè fi gbè é. Bí èyí bá rí bẹ́ẹ̀, a jẹ́ pé obìnrin tí a kọ́kọ́ dárúkọ ni ó ṣe kókó jùlọ nínú gbólóhùn orin náà. Ṣùgbọ́n torí pé ète fífi igi bá ọ̀tá jà ló ṣe kókó sí ọ̀kọrin, ìdí nìyí tó fi jẹ́ pé gbólóhùn "Bóògùn ò ràn wọ́n; Ẹ kógi bò wọ́n" ló kọ́kọ́ sọ.

Ohun tí a tún fẹ́ kí á kíyè sí nínú ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ni pé, bí kò bá ṣe ọgbọ́n àti orin ewì tí àwọn kan fi ta àwọn ọmọ ìṣòrò àti àwọn ènìyàn yòókù tó wà ní ibi ìṣẹ̀lẹ̀ náà jí ni, ó ṣe é ṣe kí àlùfáà Kamar-ud-deen ti gbé orí Lájọ̀run lọ. Ohun tí a rí tí a fi sọ báyìí ni pé, níṣe ni Lájọ̀run, tó kọ́kọ́ dé ibi ìṣẹ̀lẹ̀ náà, fúnra rẹ̀ ti ṣọ fún àwọn onílù àgẹ̀rẹ̀-orò rẹ̀ pè kí wọ́n pàlù tó sì jẹ́ pé bẹ̀nbẹ́ àwọn ìjọ̀ yìí ló ń jó bí òkòtó. Torí náà bí kò bá ṣe orin (ewì) tí ó ta àwọn ènìyàn jí láti dá irú ọgbọ́n yìí àlùfáà náà kì bá ṣẹ́gun tí kò bá sì sọ ara rẹ̀ di pàtàkì.

## 4.0 Àgbálọgbábọ̀

Kókó ohun tí a fìdí rẹ̀ múlẹ̀ níbí ni pé ọ̀kan lára àwọn ète tí Yorùbá máa ń lò láti fi jagun ni ewì jẹ́. A ṣọ àwọn ìtàn ogun nínú èyí tí a ti ṣe àmúlò ewì gẹ́gẹ́ bí ète ogun. A sọ irúfẹ́ ewì tí a ṣe àmúlò lójú ogún, bí a ti ṣe lò wọ́n àti ìdí pàtàkì tí ète ewì náà fi mú àwọn ọ̀tá tí a dẹ wọ́n fún. Ìwádìí yìí fi hàn pé a le lo ewì gẹ́gẹ́ bí ète ìdẹ́rùbani, ìdájàsílẹ̀, ìránnilétí, ìtannijẹ, ẹ̀bẹ̀ àti àyẹ́sí lójú ogun. Àwọn ìlò ewì wọ̀nyí ni ètè pàtàkí tí ó mú àwọn tí ó lò wọ́n ṣẹ́gun ọ̀tá. A fi hàn nínú àlàyé wa pé bí a ti ṣe le fi ewì dógun sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àwọn onílù Ibá ṣe ṣe nínú ogun Ìjàyè, tí a lò ó fún ìṣẹ́gun gẹ́gẹ́ bí Ògúnmọ̀lá ṣe fi mú Kúrunmí náà ni a le lò ó gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìyanjú aáwọ̀. Èyí ni àpẹẹrẹ Aṣawo àti Eléńre tí a ṣe. Ohun tí èyí ń sọ nípa ewì ni pé, "Ilẹ̀ tó bá ṣojú ẹni ṣú òòkùn rẹ̀ kì í ṣòro rìn" àti pé "Ènìyàn tó màtidé olú-ǹnàgó ni yóó mọ àtilọ rẹ̀". Ìwúlò méèjì yìí fi ewì hàn gẹ́gẹ́ bí idà olójúméjì. A fẹ́ kí àwọn olórí àwùjọ, àwọn ọba, ìjọba àti àwọn olórí ẹ̀sìn gbogbo máà gbìyànjú láti máa ṣe àmúlò ète ewì lọ́nà tó báwùjọ

òde-oní mu fún yíyanjú àwọn aáwọ̀ tó máa ń ṣẹlẹ̀ láwùjọ dípò lílo agbára/ipá tí wọ́n máa ń lò lọ́pọ̀ ìgbà. Bí a bá ṣe èyí, yóò fi àwùjọ wa hàn gẹ́gẹ́ bí àwùjọ tó ń ṣe àmúlò àwọn ohun ogún ìbí rẹ̀ láti yanjú ìṣòro rẹ̀. Yóò sì mú kí á le máa ṣe ìwádìí nípa bí a ṣe le lo àwọn ohun abẹ́lé wa fún ìdàgbàsókè àwùjọ wa.

## Ìwé Ìtọ́kasí

Abíọ́dún, T., 2013. "Kúrunmí: Valiant Warrior", *The Nation,*thenationonline.ng.net>kunrunmi-valiiant-warrior.

Adébọ̀wálé, O., Olúmúyìwá, T. àti Aṣíwájú, J. 2018. "Àyẹ̀wò Ogun Ẹnu Nínú Àṣàyàn Fíìmù Àgbéléwò Yorùbá", nínú *Yorùbá: Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria*, vol. 9 no. 1, o.i. 1-23.

Adéoyè, C. L., 1979. *Àṣà Àti Ìṣe Yorùbá*. Ìbàdàn: Oxford University Press.

Ahlul Bayt Digital Islamic Library Project, 2017. "Battle: The Life of Muhammad, The Prophet", Ahlul Bayt Digital Islamic Library Project, www.al-islam.org

Arógundádé, N.O. 2017. "War and Diplomacy", nínú *Customs of the Yorùb*á, Olóòtú, Falọlá àti Akíntúndé Akínyẹmí, o.i. 647-657.

Awẹ́, B. 1975. "Notes on Oríkì and Warfare in Yorùbáland" nínú *Yorùbá Oral Poetry*, Abímbọ́lá Wándé, Ẹka-ẹ̀kọ́ Èdè Ilẹ̀ Adúláwọ̀ àti Lítíréṣọ̀, Yunifásitì Ifẹ̀, o.i. 267-292.

Cleretian Publication, 2003. *The Holy Bible King James Version*. China: Franchrix Publisher.

Dáramọ́lá àti Jẹ́jẹ́, 1975. *Àwọn Àṣà Àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá*. Ìbàdàn: Onibọn-Òjé Press.

Faṣehun, M.A. 2018. "Ipa Tí Ogun Ẹnu ń Kó Nínú Àwùjọ", nínú *Yorùbá: Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria*, vol. 9 no. 1, o.i. 76-103.

Finnegan, R. 2012. *Oral Literature in Africa*. United Kingdom: Open Book Publishers.

Fitzgerald, 2017. *Ancient Greece War, Finer Timer (Excellent in Content).* www.thefinertime.com.bloomsbury.com

Gates, D. 2001. *Warfare in the Nineteenth Century*. New York: Palgrave.

Johnson, O. S. 1921. *The History of the Yorùbá: from the Earliest Time to the Beginning of the British Protectorate.* London: Routledge and Kegan.

Ògúndèjì, P.A., 1991. *Introduction to Yorùbá Oral Literature (Ìfáárà Sí Lítíréṣọ̀ Yorùbá).* Ìbàdàn: Ìbàdàn Distance Learnimg Centre.

Ọdúnjọ, J.F. 1971. *Aláwìíyé*: Ìwé Kẹfà. Ìkẹjà: Longman Nigeria PLC.

Ọ̀wọ́adé, S.C. 2018. "Ipa Pàtàkì tí Orin ń Kó Nínú Ètò Ogun Jíjà Nílẹ̀ Yorùbá", nínú *Yorùbá: Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria*, vol. 9 no. 1, o.i. 131-156

Pomeroy, et'al 2004. *A Brief History of Ancient Greece*: *Politics, Society and Culture*. New York: Oxford University Press.
Ramakrishna, 2015. "The Truth about Alexander", hinduwebsite.com
Riffatarre, M. 1978. *Semiotics of Poetry*. Bloomington: Indiana University.
Shiffered, S.J., 2005. "A List of Remarkable Bible Battles", godsbreath.net
Sotunsa, Mobolanle E., 2005. Features of Talking Drum Poetry, Iṣẹ́-Ìwádìí fún Gbígba Oyè Ph.D ní Ẹka-Ẹ̀kọ́ Èdè Gẹ̀ẹ́sì, Yunifásì Ibadan, Nigeria.
Townshend, C. 2000. *The Oxford History of Modern War.* New York: Oxford University Press.
Yémitàn àti Ogundélé, 1970. *Ojú Òṣùpá: Apá Keji.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Àwọ**n Abẹ́nà-ìmọ̀ tí a Ṣ**àmúlò **Ọ̀rọ̀ Ẹnu Wọn**

Fágbénlé, Awólọ́wọ̀ 2021. "Ìfọ̀rọ̀wánilẹ́núwò Nípa Aṣawo àti Eléńre" tó jẹ́ ọmọ ìlú Ayétẹ̀, Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́, Nigeria.
Lawani, Wahabi Àyísá, 2004. "Ìtàn Fúlàní Ọlọ́ṣà tó ń Yọ Igbó-Ọrà Lẹ́nu", Agbo-Ilé Àkànní-Àwíṣẹ, Òkè-Odò, Igbó-Ọra, Nigeria.
Onígbíndé, Adébóyè, 2012. "Ọ̀rọ̀ Àpilẹ̀ṣọ Rẹ̀ Ńípa Ìlù Níbi Ọdun Ìlú", tó Wáyé Nínú Ọgbà Yunifásítì Ìbàdàn, Nigeria.